# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kerindinlogbon: Osu kefa Ojo kerindinlogbon, 2016**

**Akori Oro: Imotara-eni nikan** – Apa kini

**Eko kika: Filippi 2: 1-11**

## Afihan

Imotara-eni nikan je ohun pataki ti o nda aiye l'amu, ti o si nd'ori igbesi aiye opolopo enia kodo. Imotara-eni nikan yi je arun ti nfi ogun ja gbogbo omo adari-hurun, o sin ran bi ina ajo'pa; eyiti nmu ikoro, ibanuje, ikorira, ekun, ose ati be-be-lo wa sinu aiye awa eda enia. Gbogbo ohun buruku ti o nsele si awa eda enia ati awon ohun ti ko jeki igbesi aiye wa rorun, ni oni owo imotara-eni nikan ninu tabi ti o tipa iwa buburu yi wa.
Imotara-eni nikan yi dabi kokoro ti o nje aso awa duniyan tabi aso ti o so awujo eda-enia papo, tobe ti o fi nda awon orile-ede agbaiye ru, ti kosi jeki alafia o joba. Ti awa eda-enia bale pa iwa buburu yi re patapata kuro larin/lawujo awa enia, ile aiye yi yio rorun lati gbe; besini aiye yio si dun ju oyin lo.
Awon enia oniwa imotara-eni yi ni awon ti nse awon nkan ti yio mu ere wa fun won sugbon ti yio ba opo enia ninu-je. Ti ara won nikan ni won ma nro, ni aibikita si ohun ti yio sele si awon enia toku; niwon igbati iyorisi igbese won ba ti ma pe awon nikan.

## Awon ewu iwa imotara-eni

**Pipadanu ijoba Olorun:** Gegebi bibeli se so wipe, iwa-eri ti nse iwa imotara-eni wa l'ara awon ise ti ara. Eyi le d'ena irinajo enia si ile-ologo, ti o si tun le pa awon ise-rere ti enia ti se sehin re; ki o si tun ba ajose ti nbe larin enia ati Olorun je.
Ni iwon igbati ati ri daju wipe iwa imotara-eni yi je ese nla, e jeki a ma rin ninu Emi ni igbagbogbo gegebi ijewo igbagbo wa: ki a maba mu ifekufe ti ara se, e mase jeki a r'ipa iwa yi ninu aiye wa mo **Galatia 5: 18-21**
E jeki a fi aye gba Emi mimo lati kun aiye wa, ki o si ma dari wa, ki a maba si labe ofin mo. E mase te-si ife ti ara-ese, bi iwa imotara-eni, eyiti o le muki enia ma le jogun ijoba Olorun.

**E ro ojo-iwaju ati igbehin yin:** Gbogbo olufokansin ni lati ro ojo-iwaju won ati ibiti won yio ti lo isinmi aiyeraye won. Nitorina e gbadura ki Olorun fihan yin,

awon ohun ti iwa imotara-eni yi le baje ninu irinajo yin. Ti e ba se eyi, e je ologbon ati eniti o ni oye, lati mo wipe iwa imotara-eni yi dabi arun jeje-re ti o le se akoba fun ago-ara enia ti nse Tempili Olorun **Deuteronomi 32: 29.**
Mo gbadura wipe, ao ro igbehin wa, ki a bale ri okodoro iru ijiya/idajo ti nduro de awon okan ti nfi iwa imotara-eni se ayo yo.

**Ewu orun apaadi:** Imotara-eni nikan je ese ti o buru-jai, ti o si le muki awon ti o ni iru iwa yi pari irinajo won si ago-Satani. Okankokan ti o ba ni iwa yi je ti Esu sugbon awon ti nro-ti-omonikeji ni enia Olorun.
Ni igbati awon olori orile-ede ba ni iwa imotara-eni yi, won koni toju awon mekunnu/ara-ilu ti nbe ni orile-ede won, besini iwa-ibaje, iwa-jibiti ati etan yio gbile gidigidi ni iru orile-ede be.Iru orile-ede be ki ni isinmi bikose iwa-ipa ati rukerudo ni yio joba ni agbegbe won.
Awon enia orile-ede na yio ma ko-ise awon olori won, ese ati iwa-aibikita fun ofin yio si di pupo, nitoripe gbogbo enia yio ma le idera/oro/isodi-pupo ti ara won nikan laika orile-ede si. Nigbana ni oro inu Bibeli yio wasi imuse eyiti o wipe "Ori awon enia buburu ni a da si orun-apaadi, ati ti gbogbo orile-ede ti o gbagbe Olorun" **Orin Dafidi 9:17.** Mo gbadura wipe Satani koni ba ise ojo-pipe ati akitiyan wa je nipase iwa imotara-eni.

## Awon eko nipa imotara-eni nikan

**Awon oniwa imotara-eni je alarankan:** Bibeli so nipa ti awon enia yi wipe won dabi ojeun aja ti ki yo, ati oluso-aguntan ti ko moye: Olukuluku won nwo ona ara won, olukuluku ntoju ere re lati ekun re wa **Isaiah 56: 11.**
Gbogbo okan ti won ba ntele ife-inu tiwon nikan nitori ere je onimotara-eni. Iru awon enia yi ko ni oye Oro Olorun, toripe o ye ki won yago fun iru iwa yi. Lati isinyi lo o yeki won ma le awon ohun ti yio mu aiye derun fun awujo/ipinle/orile-ede won.

**Imotara-eni nikan kose itewogba niwaju Olorun:** Ohunkohun ti enia ba se nipase iwa iomtara-eni ko se itewogba niwaju Oluwa. Nitorina, e mase jeki iwa imotara-eni tabi igberaga dari tabi se akoso igbese kigbese ti e ba fe gbe. E mase fi ija tabi ogo-asan se ohunkohun, sugbon ni irele okan ni ki olukuluku ro awon elomiran si eniti o san ju on tikarare lo **Filippi 2: 3.**
Ara e mase ohunkohun nipase imotara-eni tabi ohun asan aiye yi sugbon ninu iwa pele/tutu ati iwa irele, gegebi Kristi ti fi apere lele.

**Sora fun awon onimotara-eni ti nwasu:** Opo ninu awon oniwasu/olukoni/alufa ninu aiye loni ni won nwasu tabi se ise Oluwa nitori ere ti ara-won-nikan. Olorun ko pe opolopo won, sugbon ainise-lowo/anikanjopon/imotara-eni ni o jeki won di alufa/oluso-aguntan apapa-ndodo.
Paulu aposteli soro nipa awon wonyi ninu bibeli wipe "awon elomiran nfi ija ati ilara wasu Kristi; awon elomiran nfi inu-rere se e. Awon ti nfi ija tabi iwa imotara-eni wasu Kristi, ko se e pelu otito-inu, ero won sini lati fikun iponju awa omo Olorun, ki won le ri aye ati fiwa sinu ide" **Filippi 1: 15-16.**
E kiyesara ki awon ti awon onimotara-eni ti nwasu maba fi yin sinu ide, toripe kosi ohun ti won ko le se nitori ere t'ara-won-nikan.

E ranti wipe ki enia je alufa/oniwasu/olukoni ko tumo si wipe o wani oju ona otito. Idi re ti Jesu Kristi se wipe "ki se gbogbo eniti npe mi ni Oluwa, Oluwa, ni yio wo Ijoba Orun: bikose eniti nse ife ti Baba mi tin be ni orun" **Matteu 7: 21.**
Toripe enia nwasu Kristi ko tumo si wipe yio wo Ile-ologo, nitorina e gbo ikilo ti olugbala yin se, ki e si ma funra.

**Kosi eniti o le tan Olorun:** E le tan enia, sugbon e kole tan Olorun. Olorun mo awon enia onimotara-eni ati gbogbo ise ibi won. Nigbati akoko ba to, yio ro gbogbo iwa ibi won ki o to se ipinu lori awon eda wonyi **Jobu 11: 11.**
Niwon igbati Olorun da awon eletan enia mo, ti a si ti ko awon iwe-ese won sile; Olorun yio wo gbogbo ise won finifini, ki o to san won l'esan ise won. Nitorina se atunse ki o si ko iwa riro-tomolakeji.

**E gbaradi fun oko iyawo:** Kristiani ni lati wani imurasile fun bibo Jesu Kristi Oluwa wa. A ni lati ko iwa imotara-eni sile, ki a si ko Esu ati ise re sile pelu. Gegebi Paulu aposteli ti so fun awon ara Korinti ki won mura-sile de bibo on; eyin na e mura de ipadabo Oluwa **2 Korinti 12: 20.** Nigbati Jesu ba padawa se yio ba ese ati aisedede ninu aiye re?

**Ao siro ise re:** Yala o fe tabi o ko, o gbagbo ni tabi o ko gbagbo; jeki o wa ni ookan aiya re wipe erupe ni o, iwo yio si pada di erupe. Ni ojo kan ao pe wa lati siro awon ohun ti a se ni ile alaye niwaju Ite-idajo.
Gegebi bibeli ti fidi re mule wipe " a ti fi lele fun gbogbo enia lati ku lekanso, sugbon lehin eyi ni idajo" **Heberu 9: 27.** Kini ao wi ni ojo-nla yi, bi a ko ba kuro ninu iwa imotara-eni ati awon iwa buburu miran?

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose ketadinlogbon: Osu keje Ojo keta, 2016**

**Akori Oro: Imotara-eni nikan**– Apa keji

**Eko kika: Filippi 2: 1-11**

**<u>Awon ewu imotara-eni nikan</u>**

Oluwa feran wa pupo, torina, O se awon ikilo wipe, ki a kiyesara fun imotara-eni nikan ninu opolopo ese bibeli; oa menu-ba lara awon ikilo yi ni kikun larin eko yi.

**<u>Imotara-eni nikan ni nmu inira wa:</u>** Oniwasu so wipe "beni mo pada, mo si ro inilara gbogbo ti a nse labe oorun; mo si wo omije awon ti a nnilara, won ko si ni olutunu; ati lowo aninilara won; ni ipa wa; sugbon won ko ni olutunu" **<u>Oniwasu 4: 1</u>**.
Ohun ti Oniwasu se akiyesi re ni opolopo odun sehin, ti di ohun ti nsele lore-koore ni ibi gbogbo ninu aiye loni. Isele yi je ohun ti nko gbogbo enia l'ominu ti o si nfe abojuto ni kiakia. Tori awon enia nfi owo-ola gbani-loju, won nyanni-je, won si hun nnilara nitori iwa imotara-eni.
Imotara-eni nikan ni o jeki a ma ni awon enia l'ara ni ibi gbogbo labe orun; nipase be won nba aiye opolopo awon enia ti a nnilara je, ti ekun ati ose si di onje fun won. Ni igbati awon aninilara ni agbara ati ase, ti won si wani ipo tani-mamumi. Sugbon awon ti a nnilara ko ni olugbeja tabi oluranlowo.

**<u>Kiyesi ona re:</u>** Olorun nse ikilo fun awon oni-iwa imotara-eni ati awon enia buburu, ki won kiyesi ona won. <u>O feki won ronupiwada ki won si se ilaja pelu On, ki akoko ironupiwada to koja lo.</u> Olorun mo irora, wahala ati ibanuje ti won nda sile nipa iwa imotara-eni nikan; torina, O fe ki won dekun iwa buburu yi **<u>Haggai 1: 5, 7</u>**. Nitori iwa yi buru-jai, ni Oluwa se nse atenumo ikilo yi. Fun idi eyi pa iwa imotara-eni re patapata kuro ninu aiye re.

**<u>Laala imotara-eni je asan ati imulemofo:</u>** Oniwasu so wipe "gbogbo laala ati imo ise gbogbo, je ilara enikini lati odo enikeji re. Asan ni eyi pelu imulemofo" **<u>Oniwasu 4: 4</u>**.
E ma simi gbo, o dara fun enia fun enia lati ro ohun ti o nfe da l'aiye, ki o si se akitiyan lati de ipo na; toripe nipa akitiyan ni eda fi nde ipo-ola. Sugbon awon ti o fi imotara-eni nikan kun akitiyan won ni o buru, ti o si je imulemofo.

**<u>Aaimo ko tumo si ai-dese:</u>** Jowo, jeki oye ki o ye o loni wipe, imotara-eni nikan lodi si ife Olorun; torina, lati akoko yi lo, o kole so wipe o ko mo wipe ese ni. <u>Olorun ti ndiwon okan mo ero okan re,</u> yio si san fun o gegebi iwa imotara-eni re **<u>Owe 24: 12</u>**.
Fetisile, o ko le se atunwi wipe "nko mo ni" toripe oye gbogbo ero-inu enia ye Olorun. Eniti npa emi re mo, mo wipe o mo pe iwa buburu ni imotara-eni nikan, yio si san esan iwa re fun o, bi o ti ye.

**<u>Awon enia ko Kristi sile:</u>** Lowlowo, awon enia ko wa ohun ti nse ti Kristi Jesu tabi ebun orun/ebun Emi mo, ohun ti won nwa ni ife ti ara won ati awon ohun asan aiye yi **<u>Filippi 2: 21.</u>**
Lati isinyi lo, dekun lati je onimotara-eni nipa riro nipa Jesu Kristi olugbala ati oludande re ni gbogbo igba. Gbogbo ohun ti nmuki o ma ro nipa ti ara re nikan laise awon ohun ti o je koko si Jesu Kristi ni ki o pare ninu aiye re.

**<u>Igba ewu:</u>** Paulu aposteli kilo wipe, ni ikehin ojo, igba ewu yio de, ninu eyiti awon enia yio je olufe ti ara won, olufe owo, agberaga……**<u>2 Timoteu 3: 1-5</u>**. Ara, igba-ikehin ni a wa, torina, wa ni igbaradi/imurasile ki Satani maba lo awon ese wonyi pataki-julo imotara-eni nikan lati fa o lo kuro ni ona ododo.

## <u>Awon igbese lati bori imotara-eni nikan</u>

**<u>Apere ti Kristi fi lele:</u>** Niwon igbati Jesu ku nitori ese ati idande awa eda enia, o ye ki awa ti o wa laaye, mase wa laaye fun ara wa mo, bikose fun eniti o ku nitori wa **<u>2 Korinti 5: 15</u>**. Bi o ba fe jinde pelu Kristi, ya kuro ninu imotara-eni nikan, ki won si ma ro ti awon enia mo ti ara re; ninu ohunkohun ti o ba nse.

**<u>Fi oju si ona:</u>** Ni gbogbo igba, ma fi oju sona fun awon ohun ti nse ti awon elomiran, ki o mase je ife tire nikan **<u>Filippi 2: 4</u>**. Ma so/wo awon ohun ti nse ti elomiran, ki o si ma dabobo won; ni ipokipo ti o le wa.

**<u>Jeki alafia awon enia se koko si o:</u>** O ko gbodo sise fun ire ara re nikan, sugbon fun ire awon elomiran pelu. Mase wa ohun ti ara re nikan, sugbon wa ire ati alafia omonikeji re pelu **<u>1 Korinti 10: 24</u>**. O ni lati ma ro ti elomiran ni gbogbo igba. Awon ipinu tabi aba re ko gbodo je ipalara fun awon elomiran. Awon igbese re ko gbodo je ere fun iwo nikan bikose fun awon elomiran pelu.

**<u>Ran alailera lowo:</u>** Ri daju pe o nran awon alailera ninu igbagbo lowo, atipe o nran ailera won lowo nipa owo tabi ninu Emi ati itoju ti o peye. Mase gbe igbesi-aiye lati te ara re lorun, bikose lati te Olorun ati awon onigbagbo/ayanfe lorun **<u>Romu 15: 1</u>**. Ona ti o dara ju lati bori imotara-eni nikan nipe, ki o mase se ainani awon alailera enia, jeki ohun ti won nla-koja je elege ati pataki si o, ki o si ma ro ati ranwonlowo ni igba gbogbo.

**<u>Fi idi ododo re mule:</u>** Niwon igbati awon enia buburu tabi onimotara-eni ko su si, lati ro oran awon talaka; okan lara awon ona ti o le fi so ododo re di dajudaju, ti yio si ye awon enia wipe iwo ki se onimotara-eni, ni ki o ma ro oran awon talaka pelu igbese lati tan isoro won **<u>Owe 29: 7.</u>**
Fi idi ododo re mule, nipa itoju ati idajo-ododo, pelu anu sise fun awon alaini ati gbigba eto awon talaka fun won. Awon igbese wonyi ni yio jeki o yato si awon enia buburu ti ko nani tabi ka awon talaka si.

**<u>Mu olu ofin se:</u>** Ni igbakugba ti o ba nife omonikeji re gegebi ara re, o nmu olu-ofin Oluwa se, besini o npa iwa imotara-eni re kuro ninu aiye re **<u>Jakobu 2: 8</u>** Okankokan ti o ba fe se daradara ninu irinajo re ni lati pa imotara-eni nikan ti, ki o si feran awon elomiran gegebi ara re.

## <u>Ere aini imotara-eni nikan</u>

Ibukun ni fun eniti nro ti awon alaini, Oluwa yio gba ni igba iponju **<u>Dafidi 41: 1</u>**. Ti o ba feki ibukun Abrahamu farahan ninu aiye re, ki o si ni ayo kikun ni gbogbo igbati iwo yio lo loke erupe; mase je onimotara-eni, sugbon beresini se itoju awon alaini. Sanu fun awon talaka, ki Oluwa ba le gba o ni kuro ninu isoro re.

Lakotan, ara, e jeki a ye ara wa wo, lati ru ara wa si ife ati si ise rere **<u>Heberu 10: 24</u>**. Lati wakati yi lo bere-sini ro awon ona ti yio jeki awon enia ji-giri lati ru okan won si ife ati ise rere.

**<u>Edidi: Romu 13: 8</u>**
E mase je enikeni ni gbese ohun kan, bikose ki a feran omonikeji wa: nitori eniti o ba feran omonikeji re, o ko ofin ja.